# ÌPÈ IHINRERE ATI OJUṢE TI O N TẸLE E

## Matteu 11:20-30

## ẸKỌ 82 – FUN AGBA

**AKỌSORI: "Ẹ wá sọdọ mi gbogbo ẹnyin ti nṣíṣẹ, ti a si di ẹrù wuwo le lori, emi o si fi isimi fun nyin" (Matteu 11:28).**

**I A Bá Awọn Ilu Kan Wí**

1. A bá Korasini ati Bẹtsaida wi nitori wọn kọ̀ lati ronupiwada, Matteu 11:20; Owe 1:24-31; Jeremiah 44:5, 6
2. I ba ṣe pe a ti ṣe awọn iṣẹ́ agbara nla ti Jesu ṣe ni Tire ati Sidoni, awọn eniyan ibẹ i bá ti ronupiwada, Matteu 11:21; Luku 10:13; 11:31; Ifihan 2:21; Luku 13:2-5
3. Tire ati Sidoni yoo sala pẹlu ijiya diẹ, ṣugbọn Kapernaumu ti a gbega soke Ọrun ni a o mú sọkalẹ lọ si ọrun apaadi, Matteu 11:22-24; 23:12; Isaiah 14:13-15; Ẹkun Jeremiah 2:1, 2

**II Ihinrere Fara Sin**

4. Ihinrere fi ara sin fun awọn ọlọgbọn ati amoye, a si fi i hàn fun "awọn ọmọ-ọwọ́", Matteu 11:25, 26; Orin Dafidi 8:2; 1 Kọrinti 1:19; 2 Kọrinti 4:3
5. A fi ohun gbogbo le Ọmọ Ọlọrun lọwọ, Matteu 11:27; Johannu 3:35; 13:3; Heberu 2:8; I Kọrinti 15:27, 28

**III Ipè Ihinrere**

6. A ṣe ileri isinmi fun awọn alaarẹ ati awọn ti a di ẹru wuwo le lori bi wọn yoo bá wá, Matteu 11:28; Isaiah 53:4; 28:12; Ẹksodu 33:14
7. Ajaga Rẹ̀ rọrun, ẹru Rẹ̀ si fuyẹ, Matteu 11:29, 30; 1 Johannu 5:3

## ALAYE

### A Sọrọ Idajọ

Jesu lo akoko ti o pọ ju lọ ninu iṣẹ iranṣẹ Rẹ̀ ni agbegbe Okun Galili. O ṣe iṣẹ iyanu pupọ laaarin awọn ara Galili; sibẹ ọkàn awọn eniyan naa le o si kún fún aigbagbọ́. O fi iran naa wé awọn ọmọde ti wọn jokoo laaarin ọja ti wọn si n pe awọn ọrẹ wọn pe, "Awa fun fère fun nyin, ẹnyin kò jó; awa si ṣọ̀fọ fun nyin, ẹnyin kò sọkun" (Matteu 11:17). Johannu Baptisti dé, o n gbawẹ o si n ṣọfọ, o n waasu ironupiwada fun wọn; ọpọ eniyan ni kò kaanú fun ẹ̀ṣẹ wọn. Ọmọ Eniyan de pẹlu Ihinrere ayọ igbala; O wo olokunrun sàn, O si mú adetẹ lara dá; ṣugbọn inu ọpọlọpọ wọn kò dun.

Nigba naa ni O bá ilu wọnni wí nibi ti O ti ṣe ọpọ iṣẹ iyanu nla. O si wi pe, bi o ba ṣe pe a ti ṣe iṣẹ iyanu wọnni ni Tire ati Sidoni, awọn ara ilu naa i ba ti ronupiwada tipẹtipẹ ninu aṣọ ọfọ ati eeru. "Ati iwọ Kapernaumu, a o ha gbé ọ ga soke ọrun? a o rẹ̀ ọ silẹ si Ipo-oku; nitori ibaṣepe a ti ṣe iṣẹ agbara ti a ṣe ninu rẹ ninu Sodomu, on iba wà titi di oni. Ṣugbọn mo wi fun nyin, yio san fun ilẹ Sodomu li ọjọ idajọ jù fun iwọ lọ." Eyi fi hàn pe bi ọdun ti n yi lu ọdun ni ọkàn awọn eniyan n yigbi si i. Kò ya ni lẹnu ti Oluwa fi beere pe, "Nigbati Ọmọ-enia ba de, yio ha ri igbagbọ́ li aiye?"

Bi Oluwa bá ba ilu wọnni wí nigba ti imọlẹ Ihinrere ologo ṣẹṣẹ bẹrẹ si i tàn sori ayé, ki ni yoo ti ri fun awọn eniyan ti ọjọ oni ti wọn wà labẹ imọlẹ Ihinrere Arọkuro Ojo?

### Ojuṣe

Jesu sọ fun awọn Farisi ni ọjọ kan pe, "Awọn ara Ninefe yio dide pẹlu iran yi li ọjọ idajọ, nwọn o si da a lẹbi: nitori wọn ronupiwada nipa iwasu Jona; si wò o, ẹniti o pọ̀ ju Jona lọ mbẹ nihinyi" (Matteu 12:41). Itan Jona fi hàn gbangba ẹru wuwo ti o wà lori awọn eniyan Ọlọrun lati sọ itan naa, ati aigbọdọ-ma ṣe ti o wà pẹlu lori awọn ti o n gbọ́ ọ. Jona gbiyanju lati kọ iṣẹ́ naa silẹ nipa sisá lọ kuro niwaju Oluwa. Nigba naa ni o bọ́ sinu wahala, o si ke pe Oluwa fun iranlọwọ. Oluwa ran an lọwọ, ṣugbọn sibẹ Jona ni Ọlọrun fi iṣẹ́ naa le lọwọ lati waasu ni Ninefe.

Lọjọ oni gbogbo awọn eniyan Ọlọrun ni aloore lori odi. Iṣẹ wọn ni lati sọ ti idajọ ti o n bọ̀ fun araye. Bi awa gẹgẹ bi Onigbagbọ ba kilọ fun awọn eniyan, bi wọn ba si feti si ikilọ naa, ọrun wa yoo mọ́, awọn eniyan pẹlu a si bọ́ lọwọ ikú; ṣugbọn bi a kò ba kilọ fun wọn, Oluwa wi pe Oun yoo beere ẹjẹ wọn lọwọ wa (Esekiẹli 33:1-9). Gẹgẹ bi aloore, ipe wa ga, ojuṣe wa si tobi pupọ.

Nigba pupọ lẹyin ipade, awọn iranṣẹ Ọlọrun a sọ pe, "A ti sọ itan naa fun yin ninu orin, ninu ẹri ati ninu wiwaasu Ọrọ naa; iṣẹ ti wa ni eyi. Nisisiyii o wá kù si ọwọ́ yin; ẹyin yoo ha gba a, tabi ẹ ó kọ̀ ọ́?" Ọpọ eniyan ni o ti wariri labẹ idalẹbi ẹri-ọkàn, bi a ti n waasu idajọ Ọlọrun lati ẹnu alufaa ti o kún fún Ẹmi Ọlọrun; ṣugbọn gẹgẹ bi Fẹliksi igba laelae, wọn a fi ọjọ igbala wọn di akoko ti o wọ̀, o si le wá yọri si pe wọn kò ni ri akoko miiran ti o wọ̀ mọ́ laelae.

Ohun iyebiye ni Iye Ainipekun jẹ́ ti a kò le fi ṣire rara: ẹda ti o mọ ọ̀la kò sí. "Loni bi ẹnyin ba gbọ́ ohùn rẹ̀, ẹ máṣe sé ọkàn nyin le" (Heberu 4:7).

### Aigbagbọ́

"Nitori Ọlọrun kò rán Ọmọ rẹ̀ si aiye lati da araiye lẹjọ; ṣugbọn ki a le ti ipasẹ rẹ̀ gbà araiye là. Ẹniti o ba gbà a gbọ́, a ko ni da a lẹjọ; ṣugbọn a ti da ẹniti kò gbà a gbọ́ lẹjọ na, nitoriti kò gbà orukọ Ọmọ bibi kanṣoṣo ti Ọlọrun gbọ́' (Johannu 3:17, 18). Awọn ara Kapernaumu ti ri iṣẹ ami nla; sibẹ, wọn kọ̀ lati ronupiwada ati lati gbagbọ́. Irugbin ti a gbin sori apata lai ni erupẹ ti yara kú. Bi ọkàn ba ṣi paya, irugbin naa -- Ọrọ Ọlọrun – yoo ta gbòngbò

jinlẹ, yoo si so eso si iye ainipẹkun, omiran ọgbọọgbọn, omiran ọgọtọọta ati omiran ọgọrọọrun.  Ọrọ naa yè o si lagbara ṣugbọn gẹgẹ bi ẹda ti a fun ni ominira ifẹ ọkàn rẹ, olukuluku eniyan ni agbara lati gba a tabi lati kọ́ ọ́.

Ọpọlọpọ awọn ilu wa lonii ni wọn n pafọ ninu ẹ̀ṣẹ ati aigbagbọ́ gẹgẹ bi awọn ara Korasini ati Bẹtsaida.  Wọn ti gbọ́ otitọ ṣugbọn wọn ti yí pada si eto isin ode ara, ẹgbẹ okunkun ati ẹkọ imọ́ giga ati ẹkọ́ ti wọn n kọ́ ni pe lati inu légbélègbé ni ohun alaaye gbogbo ti jade wà (evolution).  Ọpọlọpọ ẹlẹsin ni afarawe iwa-bi Ọlọrun ṣugbọn wọn sẹ́ agbara rẹ.  Ọrọ Ọlọrun kilọ fun ni pe "Yẹra kuro lọdọ awọn wọnyi pẹlu" (2 Timoteu 3:5).

**A fi I hàn fun awọn Ọmọ-ọwọ́**

Jesu dupẹ lọwọ Baba pe O ti fi nnkan wọnyii pamọ fun awọn ọlọgbọ́n ati awọn amoye.  O si ti fi i hàn fun awọn ọmọ-ọwọ́.  Paulu wi pe, "Kì iṣe ọ̀pọ awọn ọlọ́gbọn enia nipa ti ara, ki iṣe ọ̀pọ awọn alagbara, ki iṣe ọ̀pọ awọn ọlọlá li a pè" (1 Kọrinti 1:26).  Ninu Johannu 1:12, a ka pe, "Ṣugbọn iye awọn ti o gbà a, awọn li o fi agbara fun lati di ọmọ Ọlọrun, ani awọn na ti o gbà orukọ rẹ gbọ́."

Ki i ṣe nitori Ọlọrun kò fẹ ki wọn ri nnkan wọnyii ni O ṣe pa wọ́n mọ́ kuro loju awọn ọlọ́gbọn ati awọn amoye. Ọlọrun ti fi ara Rẹ hàn tẹlẹ nipa awọn ohun ti O dá, iṣẹ ọwọ Rẹ gbogbo ati nipa Ọrọ Rẹ, ṣugbọn awọn ọlọgbọ́n ati amoye ti kọ Ọlọrun, wọn si ti gbé imọ ti wọn kalẹ, pupọ eyi ti kò gba Ọlọrun ni Ẹlẹda. Ọkàn wọn ṣokunkun nitori wọn kọ̀ lati gba ododo Ọlọrun ti i ṣe ti igbagbọ́; wọn tiraka lati gbé ododo ti ara wọn kalẹ. Ni pipe ara wọn ni ọlọ́gbọn, wọn di aṣiwere (Romu 16:22).  "Ọlọrun ti yàn awọn ohun  wère aiye lati fi dãmu awọn ọlọgbọ́n; Ọlọrun si ti yàn awọn ohun ailera aiye lati fi dãmu awọn ohun ti o li agbara. . . . . ki o máṣe si ẹlẹran-ara ti yio ṣogo niwaju rẹ̀" (I Kọrinti 1:27, 29).

**Ajaga**

Gẹgẹ ti ede wa, "àjaga" jẹ ohun elo igi ti a fi so awọn ẹranko meji pọ̀ ni ọrùn ki wọn le jọ maa fa nnkan kan ni ifọwọsowọpọ lọ si ọna kan naa.  Bi ọkan ninu awọn ẹranko yii ba lọ siwaju ti ọkan ba si fa sẹyin, àjaga naa yoo nira.  Jesu wi pe, "Ẹ gbà ajaga mi si ọrùn nyin, ki ẹ si mã kọ́ ẹkọ́ lọdọ mi" (Matteu 11:29).  Ki i ṣe pe O fẹ ki a gba àjaga Rẹ ki a si so wa pọ̀ pẹlu Rẹ nikan, ṣugbọn O fẹ ki a kọ́ bi a ti i jumọ ṣiṣẹ pọ̀ pẹlu Rẹ ati bi ati i ṣiṣẹ fun Un. Bi a ti n kọ́ lati wà ni ọgangan ifẹ Rẹ, ajaga naa yoo rọrun, ẹru naa a si fuyẹ.  Ṣugbọn bi a ba fa sẹyin nigba ti Oun n fẹ mu wa tẹ̀ siwaju a oo ni iṣoro.  Ọrọ naa wi pe o dara ki a gbé àjaga ni igba-ewe wa (Ẹkun Jeremiah 3:27).

Nigba ti Sọlomọni kú ti awọn eniyan si wá sọdọ Rehoboamu lati fi i jọba, wọn wi fun un pe, "Baba rẹ mu ki àjaga wa ki o wuwo: njẹ nisisiyi iwọ ṣẹkù kuro ninu ìsin baba rẹ ti o nira, ati àjaga wuwo rẹ̀ ti o fi bọ̀ wa lọrun" (2 Kronika 10:4).  Ṣugbọn ọba titun naa kò feti si wọn.  Eṣu kò jẹ mu ẹrù fuyẹ. Jesu maa n gbé ibi ti o wuwo jù, Oun a si mu ki ẹrù fuyẹ.

**Ipè Ihinrere**

"Ẹ wá sọdọ mi gbogbo ẹnyin ti nṣíṣẹ, ti a si di ẹrù wuwo le lori."  Njẹ ko ya ni lẹnu pe ọ̀pọlọpọ eniyan ni o ṣaisan ni ara tabi ni ọkàn, tabi ti o wà ninu idamu iru miiran, ki wọn to le gba ipè Ihinrere?  Jesu mọ pe bẹẹ ni yoo ri, nitori idi eyi ni O ṣe pe awọn ti a "di ẹrù wuwo le lori," lati wá.

Awọn ti wọn wà ninu wahala lonii le wá oju Jesu, yoo si fun wọn ni isinmi.  Oluwa na apa Rẹ jade O si wipe, "Ẹ wa. . . . Emi o si fi isinmi fun nyin."  Wo bi isinmi naa ti tó!  Wo ẹru wuwo ti a gbé kuro lọ́kàn ẹniti o wá!  Ipe naa ki i ṣe fun awọn alaisan ati alaarẹ nikan, ṣugbọn o na apa Rẹ si gbogbo araye ti n ṣegbe, O si wi pe, "Ẹnikẹni ti o ba si fẹ, ki o gbà omi ìye na lọfẹ" (Ifihan 22:17).  Bawo ni Ọlọrun tun ṣe le fi oore-ọfẹ ati ipe nla Rẹ hàn fun gbogbo eniyan ju eyi lọ?  Bawo ni ayé ti n ṣegbe lọ ti le ya omugọ̀ to, ki eti wọn di si ipe nla yii ju bi ayé ti n ṣe lọjọ oni!  "Loni bi ẹnyin ba gbọ́ ohùn rẹ, ẹ máṣe sé ọkàn nyin le" (Heberu 4:7).

## AWỌN  IBEERE

1. Awọn wo ni a nawọ ipè Ihinrere sí?
2. Ki ni ẹ̀ṣẹ ti o tobi ju lọ?
3. Ki ni ipin Kapernaumu?
4. Lọwọ taa ni Ọlọrun ti fi ohun gbogbo si?
5. Awọn wo ni a fi Ihinrere hàn fun?
6. Ki ni itumọ Ọrọ ti Kristi sọ pé àjaga Oun rọrùn?
7. Ojuṣe wo ni awọn eniyan mimọ́ ni i ṣe ninu Ihinrere?
8. Lẹyin ti a ba ti waasu Ihinrere tán ni ilu kan, ọwọ́ taa ni iyoku kù sí?
9. Bi o ba ṣe pe ni Tire ati Sidoni ni Jesu ti ṣe awọn iṣẹ iyanu Rẹ, ki ni ohun ti i ba ṣẹlẹ?